Secretary to the Govt.

AWOKAN PRINCE ESUGBAYO ATI IWE AṢẸ OBA KING NBE NIHIN NI EDE YORUBA ATI OYINBO.

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD

VOL. VI. NO 28 SATURDAY, AUGUST 25, 1928. 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: Ten Shillings (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

31 AUG 1928

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nje ki o ri aye wu arun mi silẹ.


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
Dr. Earl Sloan
SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Keep away from
Fire or Flame
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd London.
England.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹta | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Osu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

AGBAKO TABI KINLA ?

Ni apa ọja Ararọmi li ọkọnrin kan ti ngun kẹkẹ Ologere bọ ninu ọsẹ tokọja, bẹni o kọlu awọn enia kan, ti nwọn si da igbati igbamu bo, tobẹ ti o fi ke ti o si bẹbẹ pe eṣi ni, a si sọpe bi nwọn ti fi silẹ ti o nlọ bẹni obinrin kan sure jade lati ile ti o wa ni tosi ibẹ ti o si sọpe on ko ri ẹwọn golu ti on fi si ọmọ on lọrun, lọgan bẹni awọn enia wọnyi tun gba le ara oke ti nwọn ni awọn o fi ọmọ Eko han, awọn si si gba kẹkẹ rẹ pe ki o lọ wa pọnun mẹta owo ẹwọn ti o sọnu na wa, ki nwọn to da kẹkẹ na silẹ fun—Ẹ nraiye tabi ẹ ko nraiye l'ode bayi ?

DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

OṢU AUGUST NLỌ!

Ninu oṣu mejila ti o mbẹ fun ọdun kan awọn oyinbo eyiyi yi ni : January titi de December, oṣu pataki ni oṣu August jẹ larin wọn, akin oṣu lo nṣe, awọn ti nwọn jẹ amoye si mọ riri oṣu na daradara a si ma nṣe akiyes wipe ohun abarimọ tabi ohun ribiribi le ma nsaba nṣẹlẹ larin rẹ ju—o si ma nsaba bọ si asiko oṣu kan ti awọn Imale ma npe ni oṣu "Safari," to bẹ ti ọpọlọpọ enia ma fi nṣọra gidigidi larin rẹ.

Ninu oṣu August li a gbọ wipe nwọn bi Ọlọla Gomina wa yi Graeme Thompson, G.C.M.G., ki Oluwa ma fi ọpọlọpọ oṣu na han gbogbo wa o, si atari rere,—Amin.

AYỌ A BA RA TIN-TIN!

Ogunlọgo enia lo nrọ lọ wo asai "*Dẹmọ*" ti nwọn ta si oke pẹtẹsi ile Ọgbẹni Makọli lojo Alamisi iyẹn ni ọjọ ti a ni iwe aṣẹ Ọba *King* wẹ ilẹ yi nipa ẹjọ Eṣugbayi Eleko ni ilu oyinbo.

ẸJỌ MAKỌLI ATI KỌLIKRIKI.

Nwọn lo pade ẹjọ ti awọn Ọlọpa pe Ọgbẹni Herbert Macaulay, C.E., ati Dokita J. A. Caulcrick, M.B., gẹgẹ bi olotu Iwe irohin *Daily News* nipa ọrọ ọtẹ Ẹtu Ibon ti o wa ninu iwe irohin na ti ọjọ kọkandinlogun oṣu June ọdun yi. Nwọn tun fi ẹjọ yi si ọjọ Alaruba ijẹrin.

"IWE AṢẸ ALAIYELUWA."

Iwe irohin *Daily News* ti o jade ni Satide ijẹjọ, ti nṣe ọjọ kejdinlogun oṣu yi, jẹki gbogbo enia ri yẹkini ", Iwe-aṣẹ Alaiyeluwa" eyiti nwọn pade ni Agbala-Afin ti o njẹ Buckingham ni ojọ kẹtala oṣu July ti o kọja yi, eyiti o nlọ si bi oṣu kan o le ọjọ bi mẹrinla loni, nipa ẹjọ Eṣugbayi Eleko ni *Privy Council—God save the King*! Ki ẹmi Ọba pẹ titi.

MỌṢALAṢI JIMỌ.

Ni owurọ ọjọ Satide to kọja ni iwọn agogo mọkanla ni a gbo wipe oyinbo Ọlọla Samuel Wilson, K.C.B., K.C.M.G., K.B.E., (Permanent under—Secretary of State for the Colonies,) lọ si Mọṣalaṣi-Jimọ (the Central Mosque) gẹgẹ bi a ti gbọ o ranṣẹ si wọn tẹlẹ ni ojo Jimọ ijẹsan lati pade rẹ nibẹ.

Awọn Jamat ti a gbọ wipe nwọn wa pade rẹ nibẹ ni wonyi : Mọmọdu Ligali (Lemọmu agba) Lemọmu Ọpẹrẹ (olori Ratibi) —Lemọmu Idoluwo, Lemọmu Alfayat ati awọn Lemọmu Ratibi miran gbogbo, Alaji Sanni Giwa, Alaji Abudu Salami, Alufa Adamu Animashawun, Ọgbẹni Abasi Ẹlẹgba (ogbufọ) ati awọn jakanjakan gbogbo.

Nigbati Ọlọla na de ibẹ, nwọn fi Lemọmu Ligali han, nwọn ki ara won daradara pẹlu ayọ ati inu didun. A si gbọ wipe o sọ wipe inu on dun lati ri wipe Lemọmu mu suru lati reti on titi on fi de ihin loni, a si gbọ wipe o sọ wipe on wa wo alafia ilu on yio si ṣe bi ọjọ mẹta ki on to pada lọ si ile.

A gbọ wipe oyinbo Ọgagun Birrel Gray sọ fun Lemomu gẹgẹ bi Ọla alejo na ti po to, ati pẹlu awọn lo nyan awọn Aṣoju Ọba King lọ si gbogbo ibiti asia Ọba King gbe wa.

Nwon ṣilẹkun oke—sorọ Mọṣalaṣi fun u, o si gun ori oke lọ patapata, (eyi ti a ro wipe ki yio ṣai ri yẹkini bi Eko ti to) lẹhinna o rin yida gbo-

gbo Mọṣalaṣi na, ki o to wa jade lọ si ile pẹlu awọn oyinbo ti nwọn sin u wa—gbogbo Jamat ti o wa nibẹ si ki i daradara tayọ-tayọ. A ki Jamat ẹ ku alejo bẹ ni ki a ma ri o!

### ỌN A 'RE O!

A gbọ wipe Aya Ọlọla Wilson ba Ọlọla Gomina wa rin irin ajo lọ si idalẹ na ni Tuesday ijarun ki Oluwa fẹ ipade wa o.

### AWỌN AGBE-POKITI KO NI ASEKO DAN?

Nigbagbo ti a ma nsaba ri awọn Agbe-pokiti igbọnsẹ pẹlu pokiti miran, ni ode ni aseko agogo mẹwa alẹ, fun iṣẹ wọn ti nwọn nṣe. Ni igba kan ri bi agogo mọkanla ko lu, nwọn ko isaba bẹrẹ-si iṣẹ wọn, (a ko sọ ti awọn Agbe-pokiti ti ile igbọnsẹ ti Ọba ti o mbẹ larin ilu) eyi yi lo mu wa bere wipe ko daju bi awọn agbe-pokiti na ni aseko pataki kan ti nwọn palaṣẹ fun wọn lati ma bẹrẹ gan—Nitorina o yẹ ki nwọn mọ wipe igbọnsẹ ki iṣe ohun ti o yẹ lati ma ru kiri larin ilu nji iwọn igbati enia ba ṣi pọ lodepapa ni iwọn agogo mẹwa alẹ ti a ma nsaba ṣe akiyesi ara wọn lode, nitoripe orun (*smell*) igbọnsẹ ko yẹ lati ma fi imu gbọ tobẹ.

### BISHOP STREET.

Awọn *Town Council* ntun Titi Bishop Street ṣe, nipa eyi a dupẹ lọwọ wọn gidigidi, a si fẹ lati fi si iwaju wọn pe ki wọn ṣe kokari awọn Titi miran ti o yẹ fun titunṣe bi iru Bamgboṣe Street, tabi bẹ bẹ.

### PEDRO STREET.

A bẹ awọn *Town Council*, ki nwọn ṣe akiyesi wipe ile igbọnsẹ ti o mbẹ ni Pedro Street ni ẹgbẹ ile ologbe Tom Jones ko yẹ ibẹ arara, ki nwọn wa aye rẹ si ibomiran ti o yẹ—ile igbọnsẹ na wọ enia laiya pupọ fun orun (*smell*) rẹ ti opolọpọ enia ngbọ, si imu ti o ba fẹ rekoja ibẹ papa fun ilera ilu nitori irufẹ orun ile igbọnsẹ bayi ti o wa ni arin awọn enia ti nwọn si ngborun rẹ lojojumọ le fa ailera ba enia loju wa.

---

## Stop Press.

### OBITUARY.

Mrs. Comfort Aderikẹ Beckley, wife of Mr. A. O. Beckley, yesterday.

Funeral Service at St. Paul's Church, Breadfruit, to-day, at 4 p.m.

---

[L.S.]

## At the Court at Buckingham Palace

THE 13TH DAY OF JULY, 1928.

PRESENT

**The King's Most Excellent Majesty**

LORD CHAMBERLAIN
SECRETARY SIR J. GILMOUR
SECRETARY SIR W. JOYNSON HICKS
EARL GRANVILLE
SECRETARY SIR AUSTEN CHAMBERLAIN
SIR WILLIAM TYRRELL

WHEREAS there was this day read at the Board a Report from the Judicial Committee of the Privy Council dated the 19th day of June, 1928 in the words following viz :—

"WHEREAS by virtue of His late Majesty King Edward the Seventh's Order in Council of the 18th day of October 1909 there was refferred unto this Committee the matter of an Appeal from the Supreme Court of Nigeria in the matter of an Order under the hand of the Officer Administering the Government dated the 6th day of August, 1925 and also an Order under the hand of the said Officer and seal of the Colony and Protectorate of Nigeria dated the 8th day of August, 1925 under the Deposed Chiefs Removal Ordinance Chapter 78 concerning one Eshugbayi Eleko between Eshugbayi Eleko Appellant and the Officer administering the Government of Nigeria and the District Officer of Oyo Respondents (Privy Council Appeal No 127 of 1927) and likewise a humble Petition of the Appellant setting forth that on the 4th December 1925 notice was given on behalf of the Appellant that by special leave and Order of the Supreme Court Divisional Court No 2 granted on the 24th November 1925 the Court would be moved on the 8th December, 1925 on behalf of the Appellant then under the control of the Officer administering the Government of Nigeria and in the custody care and keeping of the District Officer of Oyo pursuant to an Order dated the 8th August, 1925 for leave to issue a Writ of Habeas Corpus directed to these Officer at the return thereof to bring the Appellant: to the Bar of the Court and for any further Order that the Court might deem fit to make: that an affidavit in support of the application was made by the Appellant: that in the affidavit the Appellant alleged *inter alia* that he had been illegally arrested and deported to Oyo in the Province of Oyo Nigeria and was not permitted or allowed to

leave the confines of Oyo and that he was not a person amenable to the Deposed Chiefs Removal Ordinance Chapter 78 under which the Order of deportation dated the 8th December, 1925 had been made: that the motion came before Tew J. on the 8th December, 1925 when Acting Attorney-General raised a preliminary objection to the motion namely that an exactly similar motion had already been dismissed: by the Court and that therefore the motion could not be maintained; that on the 14th December, 1925 Tew J. gave judgment that in view of a previous refusal of an identical application made in September 1925 he had no power to entertain the motion and that the motion must therefore be dismissed: that the Appellant appealed to the Full Court of the Supreme Court and on the 11th February 1926 that Court ordered that the matter should be remitted to the Court below for an affidavit to be filed by a Law Officer stating that a previous application based on substantially the grounds had been made to the Court in September 1925 and that the preliminary point should be argued and judgment given thereon that the Solicitor-General of Nigeria made an affidavit on the 9th Mach 1926 and deposed *inter alia* that on the 18th September 1925 an application had been made to the Court on substantially the same gronds as the aplication of the 4th December 1925 and that the Writ was refused on the 12th October 1925; that the matter came before Tew J. and the motion was dismissed on the 18th March, 1926; that on the 26th April Tew J. gave his reasons for dismissing the motion: that he stated *inter alia* that the grounds for the second application were substantiallly the same as those on which the first application was based and that he had no jurisdiction to entertain the application: that the Appellant appealed to the Full Court and that Court on the 10th June 1926 affirmed the Judgment of Tew J. upholding the preliminary objection and dismissed the Appeal: that the Appellant applied to the Full Court for leave to appeal to Your Majesty in Council and the application was refused: that the Appellant obtained special leave to appeal to Your Majesty in Council on the 13th May, 1927 upon depositing in the Registry of the Privy Council the sum of £400 as security for costs which condition has been complied with; And humbly praying Your Majesty in Council to take this Appeal into consideration and that the Judgment or Order of the Full Court of the Supreme Court dated the 10th June, 1926 may be reversed altered or varied or for further or other relief.

"THE LORDS OF THE COMMITTEE in obedience to His late Majesty's said Order in Council have taken the Appeal and humble Petition into consideration and having heard Counsel on behalf of the Parties on both sides Their Lordships do this day agree humbly to report to Your Majesty as their opinion (1) that this Appeal ought to be allowed and Judgment or Order of the Full Court of the Supreme Court of Nigeria dated 10th day of June 1926 and the Judgment or Order of the saide Supreme Court dated the 18th day of March 1926 set aside (2) that the case ought to be remitted to the said Supreme Court in order that the Appellant's application to that Court dated the 4th day of December 1925 may be disposed of on the evidence already filed and on any further evidence that may be placed before it (3) that the Registrar of Privy Council ought to be directed to repay to the Appellant the sum of £400 so deposited as aforesaid as security for costs and (4) that there ought to be paid by the Respondents to the Appellant his costs of the Appeal to the said Full Court his costs of this Appeal incurred in the said Supreme Court and the sum of £518. 19. 1 for his costs thereof incurred in England and that the costs of the said application to the said Supreme Court ought to abide the result of the re-hearing thereof by that Court"

HIS MAJESTY having taken the said Report into consideration was pleased by and with the advice of His Privy Council to approve thereof and to order as it is hereby ordered that the same be punctually observed obeyed and carried into execution.

Whereof the Governor or Officer administering the Government of Nigeria for the time being and all other persons whom it may concern are to take notice and govern themselves accordingly

(Sgd.) M. P. A. HANKEY

---

## ẸJỌ ỌGBẸNI MACAULAY ATI DR. CAULCRICK NI KOTU ỌLỌPA.

Ẹjọ ti awọn Ọlọpa pe Ọgbẹni Herbert Macaulay pẹlu Dr. J. A Caulcrick nipa ti ọrọ ajbọ so nipa ti tẹmbẹlẹkun ti a sọ pe awọn kan ndi lati yinbọn fun Prince Eshugbayi Eleko nigbati o ba mbọ wa si Eko lati Ọyọ, bẹrẹ ni Kotu Ọlọpa ni Wednesday ọsẹ yi

Awọn Ọlọpa pe to Ẹlẹri mẹfa nwọn pe Olori awọn Ọpa inu Ọgbẹni Ward, Ọbanikoro, Sani Adewale, ati awọn miran. Awọn Ọgbẹni Macaulay pe Ọgbẹni Braimah Igbo, Lemọmu, Sumọnu Isaka, Prince John Kọsọkọ ati awọn miran.

Ọgbẹni Kester Olori awọn Ọlọpa lo tako awọn ti a pe lẹjọ wọnyi awọn Ọgbẹni Palmer ati Ọlọla Eric O. Moore ni Lọya ti awọn Ọgbẹni Macaulya

gba : ẹri Ọbanikoro ni ṣoki ni pe on ko fẹ ki on ri oku tabi aye Eleko ki o wa si ilẹ yi, o ni awọn kan npe on ni Apania, Ole, lẹhin igbati o sọ pe nwọn ti ri ti ọrọ agbọsọ Ibọn yiyin na ka ni *Lagos Daily News* ti ojọ 28th June tokọja, Sani Adewale sọ ṣoki pe bakanna ni awọn enia ti o ka *Daily News* na npe on, pe on jẹ ọkan ninu awọn Ọlọtẹ na Ẹri awọn Ọgbẹni Braimah Igbo, Isaka ati Prince Kọsọkọ ni pe awọn gbọ agbọ sọ na lẹnu ọpọlọpọ enia awọn si gbagbọ nitorina ni nwọn ṣe lọ si ọdọ Ọgbẹni Macaulay bi Aṣaju won lati dide si ọrọ na.

Ọgbẹni Macaulay sọ pe on farablẹ pupọ lati gbọ agbọsọ yi ti orişirişi enia wa sọ fun on ni ile on lẹhin na ni on ṣẹṣẹ sọ pe ki a tẹ iwe ti on kọ na sinu *Daily News* ti ọjọ ti a nwi yi nigbati Ọgbẹni Kester sọ pe eredi rẹ ti o ko fi lẹ sọ fun awọn Olopa nigbati o gbo irufẹ agbọsọ yi, Ọgbẹni Macaulay sọ pe on lọ si ọdọ awọn Olọpa ni ẹkan ri nigbati awon mẹta kan ndi tẹ lati pa on ti nwon si fi £70 silẹ fun awon ti nwọn bẹ lọwẹ iṣẹ o ni ẹnikan na sọrọ yi fun on on si ni ki oluwarẹ kọ si iwe ki o si foruko ara rẹ si, ọkunrin na si ṣe bẹ o ni on lọ fi iwe na fun oyinbo awọn Ọlọpa Inu l' Eko nigbana, ṣugbọn nwọn ko ṣuja titi di oni

Lẹhin eyi Ọgbẹni Moore ba kotu sọrọ nipa pe ki Adajọ ri si dida awọn ti a pe lẹjọ na silẹ nitori ofin yoda pe gbigba ti awọn ti a pe lẹjọ na gba agbọsọ na gbọ ti, nwọn si fi ọro opọ ẹleri ti ki iṣe ẹṣẹ si ofin ti a fi pe wọn lẹjọ Ọgbẹni Kester, Olori şi fesi, lẹhin eyi ni Adajọ ni ki ẹjọ sun titi ọtunla nigbati on yio da ni agogo mẹsan arọ.

---

## ẸNITI O BA MỌ IṢẸ JẸ LO NJẸ OJIṢẸ.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

Nigbati baba kan wa ti o ba bi ọmọ pupọ, gẹgẹ bi a ti mọ eyiti o ba gbọ ti baba na ti iwa on pẹlu baba na ba dọgba, gẹgẹ bi ede wa, ọmọ iyẹn lo ni lati mọ ri ere baba rẹ jẹ, ṣugbọn nigbati ọran ba di ogun wipe baba kan fẹran ọkan ju ọkan lọ, ti o si yọ okan ni ipọsu, dajudaju a kole ṣẹṣẹ sọ irufẹ ero ti awọn iyoku le ni si eyiti baba won fẹran ju, ṣugbọn, nwọn ko jẹ ranti iru iwa ti ọbakan wọn nhu si baba rẹ.

Ọpọlọpọ olowo lo wa ti o jẹ wipe, nwọn bi ọmọ ọkunrin ati ọmọ binrin jọ bi idun, ti nwọn ma nsaba yi iwe-ipingun *will* pada, lọdọdun tabi loşu mẹfa-mẹfa, ẹlomiran ẹwẹ, si ma nyi iwe-ipingun tirẹ pada loşu mẹta-mẹta tabi bi o ba ti fẹ si— Kilo nmu ẹlomiran ṣe bayi ? ẹlomiran ma nyi iwe-ipingun tirẹ pada nitori iwa ti awọn ọmọ rẹ ba nhu.

Ọmọ miran wa ti o jẹ wipe bi baba rẹ ba wa ni idubulẹ aisan ti yio ṣẹṣẹ mura lati ṣe ikẹ baba rẹ, ọmọ miran si wa ẹwẹ ti o jẹ wipe bi baba rẹ ba nşe aisan ki yio kiya rẹ arara, ni ero pe ki o şi palẹmọ ki o fun wọn ni aye ki awọn ri ibi jẹ aye wọn, ṣugbọn nigbati baba wọn ba ri iwa olukuluku ngba ti ara rẹ le ati nigbati o mbẹ ni idubulẹ aisan, bẹ ni yio tişe mọ ati fun ni ogun *estate* si ninu iwe-ipingun ti nwọn nṣe silẹ de iku.

Ẹlomiran si wa ẹwẹ ti yio ni owo lọwọ dada, ti yio ko ile k'asẹ ti yio si ni ẹru *slave* lo janrẹrẹ ti yio ma ra lọ si ibikibi ti o ba wu u lati ṣe ojo rẹ, bi irufẹ oko *farm* tabi ibomiran, ti oluwarẹ ba ran ẹru kan tabi meji lọ si ibi kan pe ki o ma lo tọju ibẹ fun on, ti awon ẹru na ba de ọhun ti nwọn ba nmu iṣẹ ti oluwa wọn ran wọn ṣe, ti o ba si di igbẹhin ti omiran ba mu iṣẹ ara rẹ ṣe tabi ti o ba nşe eyiti olowo rẹ ko fi ran, tabi eyiti ko dun mọ olowo rẹ ninu rara, a ko le ṣẹṣẹ ni a nso fun nyin wipe olowo rẹ ko ni fẹran rẹ mọ—bẹni a ko le ṣẹṣẹ sọ fun nyin bi olowo wọn yio ti se ma fi ori *shea-butter* pa ikan tabi awọn iyoku lori, ṣugbon bi eyiti o ti nşe iṣẹ ara rẹ ba si tun wa ronupiwada ni ikẹhin, olowo wọn tun le fa mọra.

Ọna mẹta ati ọna pupọ ti a ko la yi lo mu ọrọ yi dani "Ẹniti o ba mọ iṣẹ jẹ lo jẹ ojiṣẹ" ṣugbọn ẹniti a ni o mọ iṣẹ jẹ nkọ o ? yio ma jẹ iṣẹ rẹ lọ titi, eyiti ko mọ iṣẹ jẹ ni iṣaju tabi ni igbẹhin ti o nmu ti ararẹ jẹ tabi eyiti o nlodi si ti owlo rẹ gẹgẹ bi a ti wi ni iṣaju ? dajudaja a ni lati da ni ẹbi, on ki yio si ya olowo rẹ mọ lat ran lọ si ibikibi bi o tilẹ sujada fun olowo rẹ na ni igbẹhin, boya ti o ba si fi ọjọ kan ṣe iṣẹ ọjọ mẹdogun fun olowo rẹ bi o ba jọ olowo rẹ loju daradara, boya ori tun le wu ni igbẹhin.

Ṣugbọn ẹniti o ba mọ iṣẹ jẹ lo njẹ ojiṣẹ, ẹniti ko mọ iṣẹ jẹ o padanu ere iṣẹ rẹ.

## DIBO FUN MI ! DIBO FUN MI !!

Akoko kan ni a ma nsaba dibo fun awọn enia ni arin ilu yi awọn ẹniti a o ba ran lọ ṣe Aṣoju ilu ni ọgba Munisiba, tabi ni Igbimọ Asofin.

Awọn ilu şe nkan ninu ọdun 1923, ọdun kẹrin oşu September, nigbati nwọn o fi yan Aṣoju mẹta si Igbimọ Aṣofin ati ninu ọdun 1926, ọdun keji tabi idunta ni ede ti Yoruba nigbati nwọn o fi yan awọn mẹta bakanna si ogba Munisiba tabi fun *Town Council* lati ma mọ ohun ti Igbimọ ba nşe ati lati ma mu ọrọ lọ pẹlu eyiti o ba jẹ ti ilu ti ki işe ti ara wọn.

Ninu aye mejeji ti a wi yi awọn ẹniti Ilu ba yan si ibẹ, nwọn ko gbọdọ jẹ iṣẹ ara wọn, iṣẹ ilu ni nwọn ni lati ma jẹ, nigbakugba ti nwọn ba nlọ pade ajọ ; nitori nwọn ti mọ aje eyiyi ni ibura ni

ede yoruba, ki nwon to lọ, eyiti ko ba fi ti ilu ṣe ninu ipo mejeji yi lẹhin ti o jẹ wipe ilu lo ran lo, dajudaju ko bikita fun awọn ilu ati Ẹgbẹ Dẹmọ ni iyẹn.

Ki a to pari ọrọ yi, adupe lọwọ Ijọba papa lọwọ Ọlọla Gomina Hugh Clifford ẹniti a ri anfani yinyan Aṣoju ilu yi si Igbimọ Aṣofin ni aseko rẹ, a si tanmo wipe Gomina wa titun yi papa Ọlọla Graeme Thomson na o le ri anfani irufẹ ohun miran bayi na fun ilu yi ni iwon igbati a mbẹ ni aseko rẹ lọwọlọwọ yi—Ki Ọba *King* papa Alaiye-luwa pẹ titi—Amin.

Nipa ọrọ wa, ṣugbọn eyiti o ba mu wa si iṣẹ ti ilu ran ti o si njẹ bi ilu ti fẹ, a ko le ṣẹṣẹ sọ bi ilu yio ti ma gbadun rẹ si, ti nwọn yio si ma ni igbẹ-kẹle si i.

Ati eyiti o njiṣẹ ilu bi ilu ti fẹ ati eyiti o njiṣẹ ti ilu ko ran tabi iṣẹ ara rẹ nigbati ẹsẹ ti tan 'lẹ bẹ ọmọ ti o ṣẹṣẹ ndide a ti rin, aseko kan mbẹ ti iṣẹ wọn ni lati pin, ti ilu yio si tun mura lati fi ẹlomiran rọ 'po, bi si wa a nwi, a kole ṣẹṣẹ sọ wipe eyiti ilu ba gbẹkẹle julọ, ni nwọn yio fẹ lati jẹki o ma ba iṣẹ wọn lọ ; nigbawo ni akoko na yio to ? akoko na de tan, gẹgẹ bi ibere wa isisiyi, bawo lo ti jina si ? Ah ! ẹnikeji on lo wọ' mu tan yi, o ku diẹ-diẹ rebete.

Ti o ba di ni oṣu September to mbọ yi ogunjọ rẹ ni yio di ọdun marun gbako ti a yan Ọlọla Lọya J. Egerton Shyngle, Ọlọla Lọya Eric. O. Moore, ati Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi-Jones si Igbimọ Aṣofin fun aṣoju ilu Eko yi gẹgẹbi anfani ti Ijọba Gẹsi fun wa ni ilẹ yi ati fun awọn ibomiran pelu—Ṣugbọn Ọlọla Lọya J. Egerton Shyngle, Ologbe ni ọjọ kọkandinlogun oṣu March, ọdun keji o le oṣu marun, ilu si yan Ọlọla Dokita J. A. Caulcrick si ipo rẹ ni ọjọ ọgbọn oṣu April, ọdun 1926, wayi o, ati Lọya Shyngle ti o ti lọ jẹ Ọlọrun nipe ati awọn ti Ọlọrun na ṣi ri ki nwọn ma mi i, sanmani ti wọn yio pe ni Igbimọ Aṣofin loṣu to mbọ eyiyi ni ọdun marun ti won ani ti nwon yio tan kew wnn, bi Ọlọrun yio tun wa pe wọn pada eyiyi ni a ko mọ iṣẹ Ọlọrun a wa ma ri di ni.

Tabi-tabi ko si ninu eyi wipe awọn mẹta ti ilu yan si Igbimọ Aṣofin ti nwọn si nba iṣẹ ti ilu ran wọn bo titi aseko won yio fi ka 'sẹ nilẹ loṣu to mbọ yi—ilu tun ni lati yan awọn ẹlomiran sibẹ, ti nwọn yio tun ma ba iṣẹ ilu niṣọ, nigbana ni awọn ẹniti ilu fẹ yan ati awọn ẹniti o fẹ yan ara won gẹgẹ bi awọn ẹlomiran ti ṣe ni ọdun karun yio fẹ ki gbogbo enia dibo fun wọn, ani nigbana li a o ma gbọ dibo fun mi ! dibo fun mi !! kakiri gbogbo adugbo, ṣugbọn o daju wipe awọn ẹniti ilu ba yan ni ẹṣin wọn le tete sure gere wọ ajọ Igbimọ Aṣofin, ti ilu yio si bẹ lowẹ lati ma jẹ iṣẹ ohun ti nwọn ba fẹ ni ibẹ, nitori ẹnikan ki jẹ awa-de.

Ko si ọmọrankan ti o nmọ oyun igbin, ko i ti si ninu wa nisisiyi ti o le mọ awọn mẹta ti ilu tun le gbe iṣẹ ilu le lowọ laseko yi, bi ko di igbati nwọn ba ṣe ikede rẹ si eti gbogbo ara ilu ti awọn ilu yio si dide lọgan lati gbaruku ti wọn lẹsẹ, ki ẹṣin wọn ma ba ṣẹ lẹsẹ lati sure wọ ibiti a mọ ni afin-ọla, ni ajọ Igbimọ na.

Ohun ti o wu wa julọ ni wipe inu wa iba dun julọ bi awọn Ijọba ba le sọ awọn aṣoju ilu mẹta na di mẹfa tabi jubẹ lo.

Ṣugbọn ki a ma reti aseko na ki Oluwa ṣọ wa di igba na lati tun wo 'ran awọn ẹniti ilu yio tun mu ati awọn ẹniti nwọn yio tun mu arawọn boya o le ri bọ lotẹ yi, nitori awọn meje li a ko mọ ẹniti o yan wọn ni ọdun karun, ti nwọn si nfẹ ki awọn enia dibo fun wọn ati ni ọdun 1926, nigbati awọn mẹta omiran si tun dide bakanna pẹlu ki awọn enia dibo fun wọn—wayi o, iṣẹ tani awọn ti a wi wọnyi yio lọ jẹ ni ohun? Ati pẹlu tani ẹniti o nran wọn lọ ? Ki Oluwa ma jẹki a ri dasi o!

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.


INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọduorun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, AUGUST 25, 1928.

## PRINCE EṢUGBAYI ELEKO, O MA KU EWU O, EWU INA KI PA AWODI; AWODI O KU EWU.

Pẹlu ayọ ati inu didun ni gbogbo Ilu fi ka Iwe Aṣẹ Ọba-King ti o de lọṣẹ to kọja eyiti a si tẹ sinu *Lagos Daily News* ti ọjọ Satide ijẹjọ. Ko si ẹniti yio ka Iwe Aṣẹ na ti ki yio kan sara si eto ati alaye ọrọ ti o mbẹ nibẹ eyiti awọn Adajọ ti nwọn gba ọrọ Apili na, làyé, Ọba-King ati awọn Ẹmẹwa rẹ: ẹda Iwe Aṣẹ yi ni a si da sinu *Eko Akete* ti oni.

Dide Iwe Aṣẹ yi fi ọkan olukuluku enia ti o ti njaya pe njẹ ẹjọ ẹni wa na tun le di riro bayi; ni Kotu ganran *Nigeria* fọkan balẹ pe laisi aniani ọsan ti o gbe alumọ lọ soke si tun mura tan lati gbe alumọ sọkalẹ itumọ eyi nipe kikọ ti kotu kọ nijelo lati gbọ kintinkintin ẹjọ na ki yio si mọ; ninu palaba ninu ṣigidi ẹrẹkẹ a ṣe'kan.

Ohun ti a tun ṣakiyesi ninu Iwe Aṣẹ na ni pe Ọba-King pẹlu awọn Ẹmẹwa rẹ pã laṣẹ pe ki Gomina *Nigeria* tabi Adele tabi awọn ti ọrọ na kan mura si laipẹ lọ titi lati ṣe abojuto gbogbo ọrọ inu Iwe Aṣẹ na: nipa eyi gbogbo enia lo ni tanma pe ẹjọ na yio tun de kotu Ganran ni ọjọ ti ko ni pẹ lọ titi gẹgẹ bi Iwe Aṣẹ yi ti de, sibẹsibẹ a gbọ pe awọn kan wa ti nwọn ndapara ti nwọn si nyọ ṣuti pe, pẹpẹṣẹ "Iwe na ti jona l'okun" ati ọrọkọrọ miran. Loju tiwa a rope ara lo nta irufẹ awọn enia bẹ, nitoripe nwọn ko gbojufifo l'adiẹ ọna ti pupọ ninu wọn ro si pe ọrọ na le pari si; ko ri bẹ mọ idirẹ niyẹn ti nwọn nfẹ sisin ku ti nwọn si nfọwọ ra'mu nipa sisọrọ ti nwọn si nlanu ti atẹgun njade. Loju awọn ti a nwi wọnyi nwọn rope kete ti Ijọba ti wa Eleko lọ lati ọdun kẹta o pari sibẹ niyẹn nwọn ko si mọ pe igbana gan ni iṣẹ ṣẹṣẹ bẹrẹ fun fi fi otitọ ọrọ na han fun gbogbo aiye ri: nitorina ni gbogbo ilu kun fun ọpọlọpọ ayọ ni oṣu keji ohun nigbati Iwe Idajọ are Apili de, eyiti o dabi ilẹkun ọrọ na Iwe Aṣẹ ti o si tun tẹlẽ yi dabi kọkọrọ ilẹkun ọrọ na; ninu gbogbo ofi ọla'wọnyi a dupẹ pe Ẹni aiye nfẹ na ko ṣamodi kan daindain, lati ma le fi mọ ohun ti o nlọ ni Ilu-Ọba nipasẹ ọrọ rẹ. Gẹgẹ bi o ti ka awọn ẹlomirna lara to, o dabi ẹnipe ki ẹnikan tumọ Iwe Aṣẹ na si ede Larubawa nitoripe a gbọ pe ọgọrọ awọn Hausa ti nwọn ko mọ ede Gẹsi ni nwọn ṣe alãrò lati ka Iwe Aṣẹ na ni ede Larubawa eyiti nwọn mọ̀.

Jakejado gbogbo *Nigeria* ti Iwe Aṣẹ yide ni a gbọ pe awọn enia nho fun ayọ ati inudidun fun imọlẹ ti nwọn ri ninu Iwe na ati fun gbigba ti awọn Adajọ Ilu Ọba ti nwọn gba ọrọ ẹjọ na yẹwo, sọpe ki kotu Ganran *Nigeria* nibi ri si: njẹ nisisiyi ti ẹfufu fẹ ti a si r'idi adiẹ yi ko ha yẹ ki awọn alapara awọn ayọṣuti gbogbo ṣiwọ ninu ọrọkọrọ wọn, ki nwọn si lọ wa nkan miran ṣe nitoripe b'ale ni b'a ba ni iwọn la nba ni ṣọta mọ.

**A** ki *Prince* Eṣugbayi Eleko lode Ọyọ o ku afojuba iro Ọba-King Alayeluwa ti o gbọ ni ijẹjọ nipasẹ Iwe Aṣẹ Rẹ ti o ri gba, a si ntọrọ ilera ati ẹmi fũn ki atunbọtan ẹjọ na le yọri si rere gẹgẹ bi gbogbo Ilu ti nfẹ.

*Prince* Eṣugbayi Eleko o ku ewu Iwe Aṣẹ ti o de fun ọ yi; ti ko ba ọ ninu amodı; ti ko si de lẹhin rẹ.

O ma ku ewu o,

Ewu ina ki p'awodi,

Awodi o ku ewu.

---

O KU EWU.

Ọgbẹni Apalara Bashua bọ ni *Thursday* ọsẹ yi ninu Ẹjọ Apania ti Ijọba nba rò.

O ku ewu.

Ẹni Ọta mbuku



T'Ọlọrun mbukun

Gbere rẹ e e ẹ.

**Prince ESUGBAYI ELEKO,**

## IWE AṢẸ ỌBA KING

### NIPASẸ ỌRỌ ẸJỌ PRINCE ESHUGBAYI ELEKO.

Awọn to pesẹ ninu Ipade ti a ṣe ni Afin Ọba Alaiyeluwa ti a npe ni Buckinham Palace ni ọjọ 13 oṣu July, 1928, ni iwọnyi :—

ỌBA KING ALAIYELUWA

Chamberlain Oloye-nla
Sẹkitẹri Sir J. Gilmour
Sẹkitẹri Sir W. Joyson Hicks
Earl Granville
Sẹkitẹri Sir Ansten Chamberlain
Sir William Tyrrell

Ninu Apejọ to kẹriri yi ni a ka Iwe Idajọ kan ti awọn Adajọ Kotu Abẹsẹ Ọba King fi ṣowọ Idajọ ti nwọn da ni ọjọ 19 oṣu June, 1928, ọrọ ti o si mbẹ nibẹ niwọnyi :—

Nipasẹ aṣẹ ninu ajọ igbimọ ti ọjọ 18th October 1909 ti Ologbe Ọba King Edward Keje pa, awọn kan fi ẹjọ Appeal kan lati Kotu Ganran Nigeria ṣowọ si igbimọ yi, nipati aṣẹ ti Alabojuto Ijọba Nigeria pa ni ọjọ kẹfa osu August 1925, ati nipasẹ aṣẹ ti Alabojuto kan na yi tun pa ni ọjọ kẹjọ oṣu August 1925 eyti o fi ẹdidi ti Nigeria di ni ti alumọri ohun wiwa Oloye ti a ti ro loye lọ Ori 78. Eyiti o kan ẹnikan ti a npe ni Eṣugbayi Eleko, nipa ti ohun ti o wa larin Eṣugbayi Eleko ẹniti o ṣe Apili ati Alabojuto Ijọba Nigeria ati Alabojuto gbereko Ọyọ (gẹgẹ bi o ti wa ninu iwe Apili yi No. 127 ti ọdun 1927) ati nipasẹ ti iwe ẹbẹ ti Eṣugbayi Eleko ṣe ninu eyi ti o sọ pe ni ọjọ kẹrin oṣu December 1925. A ṣe iwe fun on pe nipa aṣẹ pataki ti Kotu Nigeria No. 2, ti 24th November 1925. A o sọrọ ni Kotu ni ọjọ kẹjọ oṣu December 1925. Nipasẹ Eṣugbayi Eleko ẹniti o wa ni kawọ Alaṣẹ Ijọba Nigeria nigbana, ti o si tun we ni itọju Alabojuto Igbereko Ọyọ gẹgẹ bi o ti wa ninu iwe aṣẹ ti ọjọ kẹjọ oṣu August 1925, ohun ti a sọ nipa ti Eṣugbayi ni pe ki Kotu fun ni aye,

ki awọn ti o mu on lọ si ọyọ tun mu on pada wa si Kotu ati fun aṣẹ miran ti Kotu le pa; pe Eṣugbayi Eleko ṣe iwe ibura nipa ọro yi ninu iwe rẹ si Kotu pe ninu iwe Ibura Eṣugbayi Eleko sọ pe a ra on mu a si wa on lọ si Ọyọ ni ọna ti o lodi si ofin. A ko si fun on laye lati fi Oyo silẹ, pe ofin riro Oloye loye ti Alabojuto Ijọba Nigeria fi lo on ko kan on. A sọ ti ẹjọ na niwaju Tew Adajọ ni ọjọ kẹjọ oṣu December 1925, eyiti Adele Agbẹjọro Ọba kuwo nipa siso pe irufẹ ẹjọ kanna yi ti wa si iwaju Kotu, pe ni ọjọ 4 oṣu December pe Tew Adajọ dajọ pe niwọn igbati Kotu ti ko ẹjọ ni September 1925 on ko ni agbara lati gba a yewo on si pa ẹjọ na loku, pe Eṣugbayi Eleko tun ṣe iwe si Kotu Arotunro ti Nigeria ni ọjọ kokanla oṣu February 1926. Kotu na paṣẹ pe ki ada ẹjọ na pada si Kotu abẹ on ki amofin onişẹ Oba kan ki o ṣe Ibura pe nwọn ti gbe ẹjọ kanna yi bayi lọ si—Kotu ganran na, ati pe ki nwon le ṣe ariyan-jiyan pe Igbakeji Agbẹjọrọ Ọba ṣe iwe ibura ni ọjọ kẹsan March 1926. Pe ni ọjọ kejidilogun 1925 iwe ti Eṣugbayi ṣe si Kotu nipa ẹjọ re o jasi ọrọ kanna gẹgẹ bi awọn iwe ti o ti nṣe bo lati ẹhin wa, Kotu si gba ọjẹgẹ fun iwe yi bayi ni ọjọ kejila oṣu October 1925, ẹjọ na wa si iwaju Tew Adajọ, nwọn si takulẹ ni ọjọ 18th March 1926.

Ni ọjọ 26 oṣu April 1926, Tew Adajọ sọ idi rẹ pe on ti o jẹ ki o ta ẹjọ na kulẹ ni pe, ọro nkan kanna ni Eṣugbayi nro lẹjọ ninu iwe rẹ eyi ti Kotu ti nta kulẹ nigba gbogbo Kotu Arotunro gba nkan ti Adajọ Tew wi; Eṣugbayi tun kowe si Kotu Arotunro pe on fẹ gbe ẹjọ on lọ si ọdọ iwọ Ọba Alaiyeluwa ṣugbọn a ko fun u, Eṣugbayi si gba aye akanṣe lati gbe ẹjọ yi wa si iwaju iwọ Ọba, nipa sisan irinwo ponun £400 si Kotu abesẹ Oba King bi iduro, o si bẹ iwọ Ọba King pe ki o gba ẹjọ on ti Kotu Eko ti da ni ọjọ kẹwa oṣu June 1925 yẹ wo, ki o si gba on lọwọ Idajọ yi. Awa Adajọ si mu aṣẹ Ọba King yi ṣẹ nipa yiyẹ ẹjọ na wo. Ohun ti a si ri nibẹ ni a sọ fun iwọ Ọba King towọ-tọwọ pe ki iwọ Ọba King gba iwe ẹbẹ ti Eṣugbayi, ki o si ko Idajọ ti nwọn da ni Kotu Eko danu (2) pe ki iwọ Ọba King da ẹjọ Eṣugbayi pada si Ganran fun titun ro lori ẹri ti o ti wa ri tabi ti o ti nri tabi ẹri titun miran ti yio tun mu wa (3) pe ki iwọ Ọba King paṣẹ pe ki a da irinwo £400 ponun ti Eṣugbayi ti fi dogo fun owo irin ẹsẹ ni Kotu Abẹsẹ Ọba King (4) pe ki awọn ti o jejo san owo £518 19 1 ti o jẹ owo irin ẹsẹ ni ilu Oyinbo fun Eṣugbayi. Ati pe owo irin ẹsẹ ti Eṣugbayi yio tun gba ni Nigeria yio fi ara ti titi gbigbo ẹjọ rẹ ni Kotu Nigeria yio fi pari sibi kan, inu Ọba King si dun si gbogbo imọran yi. O si gba ọjẹgẹ pe ki a mu gbogbo rẹ ṣẹ kiakia.

Nitorina ki Gomina tabi Oyinbo Alaṣẹ Ijọba Nigeria nisisiyi ati awọn enia miran ti ọrọ ẹjọ Eṣugbayi yi kan ma jafara lati ṣe akiyesi aṣẹ Ọba King yi o.

(Sgd) M. P. A. HANKEY.

## IROHIN ILE-IFẸ.

### ERIN FI ỌLA YI Ọ KA!

Ayọ kekere kọ ni a fi ki Ọgbẹni wa E. T. Adewọyin Coker ku abo lati Eko enili o lọ toju ara rẹ ni ile Alarun Dokita Gray ti on papa de sihin ni ọjọ Tuesday ijọ kẹrinla oṣu yi pẹlu ọrẹ rẹ Ajasa L. Mọsanya. Asi ki Baba wa Ọni Alayeluwa ati Prince Adeyẹmi ati gbogbo ẹbi yoku wọn ku atojuba.

Ọgbẹni Ajasa R. Mọsanya ẹku rin si arin wa, nigbati a lo ki alejo yi, osi sọ gbogbo iyẹsi ati inawo ti awọn Ile-Ọba ṣe fun on pẹlu awọn ọmọ Ọba. O si ni ki a ba on dupẹ-dupẹ gidigidi lọwọ gbogbo awọn to ṣe on ni alejo pataki Kabiyesi Oni Alayeluwa, Princesses Marian Adelajọ, Ọmọlajọ Jọlade ati awọn jakan-jakan miran.

Ọgbẹni E. T. Adewọyin Coker ni ọjọ Wednesday ijọ kẹdcgun oṣu yi ati Ọbẹni A. R. Mọsanya wọn da kan lọ si Oshogbo lati lọ ri oyinbo rẹ, ni abo Ọgbẹni Disu ọmọ Ogboni ti Ilesha ṣe Ọgbẹni A. R. Mọsanya ni alejo pupọ nipa op lọpọ Ọti ati nkan miran, wọn si bọ si Ile-Ifẹ ni alẹ ọjọ na.

A ko le robin awọn Ijoye pataki bi awọn Jagunọshin, Lọwa ati awọn ara Ilu bi wọn ti npara fun alafia ti wọn ri Ọgbẹni E. T. Coker pada bọ si arin wọn inu wọn si dun gidigidi lati ri, wọn si tun ki ti ọfọ to ṣẹ—nipa iku Baba rẹ ọwon—Ki Ọlọrun ko gbe si afẹfẹ rere—ki ẹhin Baba rẹ ko da.

Ọgbẹni Coker si tun sọfun wa nipa ti Ọgbẹni A. T. Shodẹhinde ti Ile-ọja John Holt & Co., ni Abẹokuta nipa Ọti orişirişi ati Cigarette Milk ti ofun on nigbati on nbọ on nbọ wa si Ile-Ifẹ. Aşiri abo ọgbẹni Shodẹhinde.

Ao fi gbogbo irohin yoku si ọsẹ to nbọ ni agbara Baba ka to le jihin rẹ.

### ỌBAJIO ỌRUN RE O.

Ọba Ejio pa ipo da lọ si bi isinmi ni ọjọ kẹfa oṣu August yi, o bọ ninu wahala aiye yi, ki Ọlọrun ko fi ọrun kẹ. Ọpọlọpọ awẹn enia rẹ ni agbole Ọbajio ni wọn du ipo nlaula yi, ṣugbọn enia mẹta ninu wọn ni nwọn ntẹ ipo na, ṣugbọn Ọwa agbole yi ni ipo yi bọ si lọwọ. Ọwa papa ti di ẹni agba, adura wa ni ki Ọlọrun ko fun ni ẹmi gigun ko si gbadun ipo Ọba rẹ na.

Ni ijọ kẹtadilogun oṣu August yi, ni ọwọ tẹ Ọgbẹni Onişegun kan to nda Aje fun awọn enia mẹtala, ti aje si mu ẹni kẹtala ẹniti aje yi mu, owa ninu amodi nla lọwọlọwọ yi. Ni ijọ kejidilogun oṣu yi ni ọwọ Ijọba tẹ Onişegun yi osi wa ni ipamọ lọwọlọwọ yi.

"A PỌN'KỌ KERE KO TO A SỌ WO MURA"

A ri ajeji kan Syrian ti a ma npe ni Korah eyiti orukọ rẹ njẹ Zard o wa gbe inu ọja Ifẹ gan, ko gbe ibiti Ijọba Ifẹ la silẹ fun gbogbo awọn ajeji alawọ funfun ni lati ma gbe, o si wa ra Cocoa lo şe kuku ngbe inu Ọja-Ifẹ, awọn ẹgbẹ onişowo Ifẹ "Ifẹ Traders Association" wọn şe iwe si Ọba Oni ko fi ọrọ na si iwaju Ajẹlẹ.

Ni ọjọ Monday ogunjọ oşu August 1928 ni Ọba Ọni ran awọn Ẹmẹşẹ meji jade ekini ni Oloye Oshinlatọ ekeji iranşẹ Ọni papa Ogunmuyide wipe ki wọn sọfun gbogbo onişowo gba ati awọn ajeji to wa raja patapata ni enia dudu wipe wọn ko gbọdọ ta egbinrin ọja fun Syrian yi ayafi to ba ko kuro ni ọja Ifẹ to si lọ gbe ibi ti ẹgbẹ rẹ ngbe. To ba ko lọ sibẹ awọn enia dudu le tọ lọ ni ọhun ki wọn ma ta fun ko le wọ. Mo ki Alayeluwa Ọba Ọni Ifẹ ati awọn Ijoye rẹ wọn ku la kaye. Mo si ki Ọshinlatọ ati Ogunmuyide won ku ohun, ẹnikẹni to ba mo awon ẹni meji yi, wọn o ri wipe wọn nşişẹ ninu amofin. Kabiyesi ki Ọni pẹ fun wa o.

A ri gbo lati gbodo wipe Ọgbẹni Coker da kan lọ si ajo ko si ni pẹ pada bọ si arin wa. Ona arelo o.

---

## *Olusakin's Column.*

---

Jubilee Service of Rev. James Jamrison Pearse.

The Jubilee Service of Rev. James Jameison Pearse, L.th., Pastor of St. Jude's Church, Ebute Metta, was celebrated at St. Jude's Church, Ebute Metta, on Saturday last, the 18th August, 1928.

The ceremonies which occupied nearly the whole day took place in the following order :—

Prayer meeting at 5.30 a.m., and Holy Communion Service at 8.30 a.m., the Right Rev. Bishop A. W. Howells, D.D., officiated.

A Thanksgiving Service was also held in the afternoon at 4 p.m., which was largely attended, conspicuous among those present may be mentioned Bishop I. Oluwole, D.D., Bishop A. W. Howells, D.D., the Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, L.th., and Mrs. Ogunbiyi, Henry Carr, Esq., M.A., B.C.L., Rev. H. V. Johnson, B.A. Rev. J. A. H. Ogunro, Rev. S. V. Latunde, B.A., W. O. Aiyedun, B.A., Rev. D. A. Hughes, Rev. J. F. Ogunko, Rev. C. A. Sowunmi, M.A., Rev. J. O. Lucas, M.A., Dr. Oguntọla Sapara, I.S.O., J. Bagan Benjamin, Esq., C.K., and Mrs. Benjamin, Dr. R. A. Savage, M.B., ch.B., C. W. Wakeman Esq., and Mrs. Wakeman, E. Jenkins Harrison, Esq., B.L., E. M. E. Agbebi, Esqr., B.L., S. A. Thomas, Esq., B.L., Adedapọ Kayọde, Esq., B.L. Olumuyiwa. Jibowu, Esq., B.L., and Mrs. Jibowu, G. T. Bickersteth, Esq., Solomon A. Shogbẹsan, Esq., J. A. Odufunade, Esq., T. B. Bukọ, Esq., J. Adolphus Roberts, Esq., J. G. Kuye, Esq., J. D. Akihanmi, Esq., B. O. Taylor, Esq., A. E. Williams, Esq. A. E. Norman Williams, Esq., D. A. Bright, Esq., J. Glover Willoughby, Esq., E. A. O. Bright, Esq., E. W. M. George, Esq., C. A. Kasumu, Esq. J. Ọmọşalewa Thomas, Esq., M. A. G. King, Esq., E. A. Shyllon, jnr., G. W. Parkin, Esq., D. O. Olubi, Esq., E. Eşuronbi, Aro, Esq., Edwin Willoughby, Esq., I. F. Maye, Esq., E. B. Smith, Esq., E. I. Kuyinu, Esq., M. A. Adebiyi, Esq., J. O. Oshoba, Esq., Rev. J. R. Williams and Mrs. Williams, J. Ayọ Ogunbiyi Esq., George Marmon Esq., S. H. Braithwaite Esq., W. A. Adedoyin Esq., P. Abisogun Esq., S. A. Sholu Esq., E. A. Bukọ Esq., Mrs. Layinka Pearse, Mrs. J. L. Oni, Mrs. C. C. Adeniyi Jones, Mrs. A. Agard, Miss Rẹmi Jones, Miss Adebisi Oni, and host of others. Bishop Howells delivered an impressive address on Rev. Pearse's work as far back as fifty years in the Mission Field where he has faithfully served from schoolmaster to Cathechist, until he was after many years of trial and discouragements probably ordained as Deacon and later to the Priest Order of the Church of England.

An address and a purse were presented by the Jubilee Celebration Committee: Address and some gifts from Ladies' Hope Society; also an Address from the Boys' Brigade through their Captain Mr. G. Sunny Lawson.

We congratulate Mrs. Pearse and wish for her and the Reverend gentleman a long life of usefulness and prosperity.

---

Promotion.

Mr. W. H. Fowler, Assistant Chief Clerk, Accounts Department, Nigerian Railway, Ebute Metta, has been promoted to the rank of Chief Clerk, as from the 1st April, 1928. congratulation.

---

"ELEKO KẸ."

A gbọ pe awọn kan fi Sanusi Olusi jẹ oye ti awọn enia na npe ni "Eleko" lana. Hun un-un-un.

### THE DEATH OF THE GREAT EMPIRE

**Viscount Haldane of Cloan, O.M., Kt., Barrister-at-Law.**

It is with deepest regret we chronicle the lamentable death of the late Right Honourable Viscount Richard Burdon Haldane of Cloan, O.M., K.T., B.L., which took place at his residence in Scotland on Sunday the 19th August, 1928.

Lord Haldane was Lord Chancellor of Great Britain from 1912 to 1915; he was Rector of Edinburgh University and Chancellor of the University of Bristol. He was called to the Bar in 1879, and took silk in the year 1890 as Queen's Counsel. His Lordship was a member of the Judicial Committee of the Privy Council where Nigeria came into close contact with him on two distinct and successful occasions, the Appeal of Chief Amodu Tijani Oluwa in the great Apapa Land Case, which he has won in July 11, 1921, and on May 9th 1927, Viscount Haldane with Lord Warrington and Lord Shaw as Lords of the Judicial Committee of the Privy Council advised His Majesty that leave be granted to Prince Eşugbayi Eleko of Lagos, in his Appeal.

The late Lord Haldane's name will alway be remembered in the whole British Empire. As a man who maintained Justice, Equity and Fairplay.

His remains were removed to Glenagles, Scotland, on Thursday, the 23rd instant for interment.

The King in a message of sympathy to the relatives says "Lord Haldane will be remembered with respect and gratitude for his service to the state and especially by all who recognised that it was chiefly due to his able administration as War Minister that 14 years ago on the outbreak of hostilities the British Expeditionary Force was promptly and efficiently mobilised and despatched abroad".

May his soul rest in peace.

OLUŞAKIN.

---

Eko,
14th August, 1928.

Si Oniwe-irohin "Eko Akete"

Iba o,

Jọwọ gba mi laye diẹ lati sọ gbolohun kan tabi meji nipa ọrẹ mi otitọ Ọgbẹni E. T. Adewọyin Coker ẹniti o wa si Eko pẹlu ailera lati Ile-Ifẹ to si de si itọju Dokita Gray, ẹniti Dokita si ti ọbẹ họ ịara ni ijọ kọkandilogun oşu June, *1928*, ayajọ ijọ ti waya Ọba wa Eşugbayi Eleko wọ ilẹ yi. Ọgbẹni Coker yi fi Eko silẹ ni ọjọ kẹrinla oşu August, 1928, ti o di oşu meje pẹlu ijọ kan ti o fi ile silẹ aya, ọmọ, ẹbi gbogbo ti o si npada lọ ba wọn.— Ayọ a bara tintin, ẹniti ko mọ riri irufẹ ewu bẹ ko wọpọ, şe enia ni wọn la bẹ ni ọjọ kan şiwaju ti Ọgbẹni wa yi, to si ba bẹ lọ si orun alakeji are ma bo, ki Oluwa ki o gbe si afẹfẹ rere, şugbọn şi fini Ọgbẹni wa yi şe lo jẹ ki o da si. Lẹhin ti Ọgbẹni wa yi wa ninu amudi ati inira lẹhin lala rẹ ni baba rẹ jalaisi ni ile-Ifẹ ti gbogbo ẹbi lọhun lo si dide si sisinku yi. Idile Ọba Ọni kabiyesi lo sin oku yi ati idile oloku papa ko kẹrẹ nipa sisin oku yi, şugbọn a ko le tu ọfọ yi fun Ọgbẹni yi lasiko na, nitori bi enia tu efọ na, ọkan ko le gun, oluwarẹ yio fa (*danger*) şugbọn a gbe gbogbo rẹ mi titi ara rẹ fi le, ki o to ranşẹ si aburo rẹ Prince Adeyẹmi ati Ọba pe oku di sisin, lẹhin eyi gbogbo nkan nlọ fun rere, ọkan ninu iyawo bi ọmọ lẹhin to file silẹ, şugbọn ọmọ rẹ obinrin kan kẹ si ku bakanna,, loju wa ko si ẹniti ọmọ şe lẹhin oluwa. Gẹgẹ bi ati sọ şiwaju şe ẹmi on papa şi wa, adupẹ lowo Ọlorun; ofi Eko silẹ ni agogo mefi aro pẹlu Motor rẹ ati awọn ọrẹ ododo ti wọn si sin lọ lati la ba dele—awa papa si fi ohun sin ati aya rẹ aburo Felicia, ati ọmọ rẹ Abiọdun ati Taiwo—Adura wa ni pe Ọlọrun ko ma jẹ ka ri aseko yi anọ, ki Oluwa ko si jẹ ko ba Ọni Nlayeluwa ni alafia ati Prince Adeyẹmi ati gbogbo ẹbi patapata ati awọn ọrẹ bi M. D. Akiyẹmi, Aderẹmi, E. O. Shanu, E. Titus Ladipọ, ati awọn jakanjakan miran, ki nkan ma si şe awa to fi silẹ nihin—asi ki gbogbo Ifẹ wọn ku afojuba ẹni ọwọn wọn.

Emi ni tirẹ nitoto,

KEKERE-IFẸ.

---

### ORI IV.

### IŞẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KỌKANLA.

---

Iwa Sir Walter Scott ni, ki o ma bu ọwọ nlanla fun awọn enia ti o mọ işẹ, awọn igi ni ona işẹ şişe; o si jẹwọ gbangba pe on ko ro pe botiwu ki enia mọ iwe to, o yẹ ki a fi we ti awọn ọga işẹ pataki—ko a ma şeşẹ sọ ti fifi we ti ọgagun ti o to ọgagun.

Ọgagun ti o to ọgagun ti o nke abamọ, a ti ro gbogbo rẹ pebe. A ro ti ohun ti ko jọ ni loju, ohun ti ko to tun. Bayi ni a ri pe nigbati Wellington jẹ olori awọn ọmọ ogun ni Spain, o ko awọn ọmọ ogun bi nwọn o ti şe onjẹ wọn. Nigbati o wa ni India o paşẹ bi nwon o ti da malu mọ; kinikini ni o şe eto ohun gbogbo ti awọn ọmọ ogun nlo. Nitorina na ni a şe ri i pe ki ki işe nwọn peye nikan ni, şugbọn nwọn ngbo tirẹ, nwọn si mọ gbangba pe o to tẹle.

## Beware of the season.

Use Dr. Skelton's Influenza and Cold Cure strongly recommended for this Owore Season 2/6d.

## That Wonderful Female Pill!

Wireless Female Pills instils new life in women, recommended for all functional disorders peculiar to women. It regulates the system and prevents barreness 4/- per bottle.

## New Life for Men.

Life Tonic Tablet will revitalise you; this wonderful Tablet costs you 3/- only. Get a bottle.

## Yaro! Yaro! Yaro!

No more pain for children cutting teeth, use 'Yaro' Infant's favourite Preservative. It prevents convulsion &c., &c. 2/3d and 3/3d per bottle.

**Do away with Piles!**

Get rid of Pile that loathsome disease by using:—

Effective Pile Remedy 7/6d

Pile Pills 1/6d

Pile Ointment 2/-

**Kaduna Balm.**

Every Home requires Kaduna Balm, the family Remedy applicable in 100 different ways. 1/-

**Don't grow old whilst you are still Young.**

Dr De Roos' concentrated Guittae Vitae will bring you back to Health and Beauty. Recommended for general debility, dimness of sight, shaking of the hands and limbs—miraculous curer £2 2s. (largest size)

**We also stock:—**

Elixir Hydrastin 10/6d
Elixir Avena with Helonias Compound. 10/6d
Sacharine 1/- & 1/6d
Male Tonic 10/6d
Cooling Blood Purifier 7/6d
Vibrona Wine 7/6d

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
*Branches*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
100 Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by Victor White, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.* *N.B.*—Not Obtainable Elsewhere. "Shake the Bottle."

### AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o nię pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ęda ati gbogbo arun ti ki ję ki okunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price Ten Shillings (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by Victor White Esq.

41, Offin Road, Lagos.

*N.B.:—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ęda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

Price 10/- Per Bottle.

Postage 2/6 extra.

## WHITE'S WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq., 41, Offin Road, Lagos.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra. Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

**N.B.**—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI IŞOYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy of Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist,*

The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price Ten Shillings (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ĘJĘ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ęda ti o ba gbo, Ęyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ęsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same,* if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune !!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

**A Trial is Solicited.**

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

**TO LET.**

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to — A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.